# AWỌN ÀMÌ IPADABỌ OLUWA

**Nahumu 2:3, 4; 2 Timoteu 3:1-5; 2 Peteru 3:3, 4;**

**Jakọbu 5:7, 8; Matteu 24:3-28**

**ẸKỌ 362 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Nitori gẹgẹ bi manamana ti ikọ lati ila-õrun, ti isi mọlẹ de iwọ-õrun; bẽni wiwá Ọmọ-enia yio ri pẹlu" (Matteu 24:27).**

## Lori Oke Olifi

Lori Oke Olifi yii gan, nibiti Jesu yoo gbe goke lọ si Ọrun, ni Jesu joko lọjọ kan pẹlu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀. "Sọ fun wa," ni wọn wi fun Jesu "kini yio si ṣe àmi wiwa rẹ, ati ti opin aiye?" Nigba naa ni Jesu sọ fun wọn nipa ogun, iyàn ati isẹlẹ gbogbo ti yoo wá sori ilẹ ayé ṣiwaju bibọ Rẹ̀. O sọ nipa awọn èké wolii, tabi awọn oniwaasu èké ti yoo tan awọn eniyan jẹ, ati nipa ẹ̀ṣẹ buburu ati wahala ti yoo wá sori ayé. O wi pe "A o si wasu ihinrere ijọba yi ni gbogbo aiye lati ṣe ẹri fun gbogbo orilẹ-ède; nigbana li opin yio si de."

Lẹyin eyi lọjọ kan Jesu tun wà pẹlu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lẹẹkan si i lori Oke Olifi, nibiti awọsanma gbé gbà A lọ si Ọrun. "Jesu na yi, ti a gbà soke ọ̀run kuro lọwọ nyin, yio pada bẽ̀ gẹgẹ bi ẹ ti ri i ti o nlọ si ọrun," ni ọ̀rọ ti awọn ọkunrin meji alaṣọ àla ti o duro leti ọdọ wọn sọ fun wọn (Iṣe Awọn Apọsteli 1:11).

## Onigbagbọ́ ati Alaigbagbọ́

Bi o tilẹ jẹ pe ẹgbaa ọdun ti rekọja lẹyin ọjọ iyanu nì, sibẹ nigba gbogbo ni awọn eniyan ti wà ti wọn n ṣọna, ti wọn n duro, ti wọn si n pongbẹ fun bibọ̀ Jesu. Lode oni, Onigbagbọ́ tootọ kò tun n wi pe, "Sọ fun wa, kini yio si ṣe ami wiwá rẹ?" ṣugbọn oun a maa wo inu Iwe Mimọ́ Ọlọrun fun awọn àmì wọnni, bi o si ti n ṣakiyesi ohun ti n ṣẹlẹ oun yoo mọ̀ daju pe gbogbo ami wọnyii ni o ti ṣẹlẹ̀. Ki ni gbogbo nnkan wọnyii n sọ fun wa? Eyi ni pe Jesu le dé nigbakuugba!

Ẹ maṣe jẹ ki a wa laaarin awọn ti wọn n ṣẹfẹ ti wọn wi pe: "Nibo ni ileri wiwa rẹ̀ gbé wà? lati igbati awọn baba ti sùn, ohun gbogbo nlọ bi nwọn ti wà ri lati igba ọjọ iwa" (2 Peteru 3:4). Ileri naa wà ninu Ọrọ Ọlọrun, a si gbagbọ́ pe a o wà laaye a o si ri Jesu nigba ti o ba n pada bọ̀.

Nitori pe ohun kan ko i ti ṣẹlẹ kò fi hàn pe ohun naa ki yoo ṣẹlẹ. Ṣaaju Ikun-omi, nigba ti Noa kan ọkọ nì, awọn eniyan kò gbagbọ́ pe ikun-omi yoo dé. Wọn n fi Noa ṣẹlẹya gẹgẹ bi wọn ti n fi awọn oniwaasu ododo ṣẹsin lode oni. Ṣugbọn lojiji, "omi de, ti o gbá gbogbo wọn lọ" (Matteu 24:39).

"Gẹgẹ bẽni wiwa Ọmọ-enia yio ri pẹlu" (Matteu 24:39). Lojiji! Fun awọn ti kò fi oju sọna fun bibọ̀ Rẹ̀. Gẹgẹ "bi ikẹkun" fun awọn ti kò wà ni imurasilẹ! (Luku 21:35). "Bi olè" fun ẹni ti kò di ara rẹ̀ ni amure (1 Tẹssalonika 5:2). "Gẹgẹ bi manamana," ti n dá eniyan niji! (Matteu 24:27). "Lãrin ọganjọ," nigba ti ohun gbogbo ṣokunkun! (Matteu 25:6).

Ọpọlọpọ "àmi" ni o wà ti o n kọ́ wa pé bibọ̀ Jesu wà lẹyin ilẹkun. Awọn eniyan Ọlọrun ti n gbé lori ilẹ ayé ṣaaju igba Kristi sọ̀rọ nipa awọn ohun ti yoo ṣẹlẹ ni ikẹyin ọjọ. Awọn ami ti Jesu sọtẹlẹ fun awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀ -- ogun, isẹ̀lẹ, idaamu – gbogbo wọn ni o ti ṣẹlẹ̀. Ọpọlọpọ awọn ọdọmọde lode oni ni o le ranti igbati wọn dagbere fun ẹgbọn wọn ọkunrin tabi baba wọn ti o lọ si ogun. Gbogbo wa ni o ti gbọ́ nipa isẹlẹ̀ ti o si ti ṣiṣẹ iparun lọpọlọpọ ni akoko tiwa yii, ati nipa iyà ati wahala ti ọ̀pọlọpọ eniyan wà ninu rẹ̀ lori ilẹ ayé.

## Awọn Arinrin Ajò

Njẹ o ṣakiyesi nigba ti o n rin irin-ajo lọ si ilu kan pe bi o ti n sunmọ ilu naa ni o n ri ọ̀pọlọpọ apejuwe ti o n fi hàn pe iwọ fẹrẹ dé bẹ? Awọn apejuwe miiran n sọ nipa ile-èro tabi ile-ounjẹ ti o wà ni ilu naa; awọn apejuwe miiran n fi bi ilu naa ti jinna tó hàn; bẹẹni awọn apejuwe miiran a maa sọ fun wa akoko ti a le lò ki a tó dé ilu naa.

Lonii a n rin irin-ajò. Olukuluku wa ni o n rin irin ajò lọ si Ayeraye, awọn ohun itọka ti o hàn gbangba si wa ni oju ọna Iye naa. Laiṣe aniani, Onigbagbọ́ arinrin-ajò naa ni iwe-amunimọna, iwe-aworan-apẹẹrẹ ilẹ ati ẹrọ amunimọna, bẹẹni a si maa farabalẹ̀ ṣafiyesi iwe-amunimọna rẹ̀, ani Bibeli. Gẹgẹ bi o si ti n rin ọ̀na ayé lọ a maa ri awọn ami oju-ọna. Yoo wo inu iwe-amunimọna rẹ̀. Yoo si ri i dajudaju pe ibiti oun dé yii wà ninu iwe-amunimana naa, bẹẹni lẹba ọna ami ọ̀na naa si wà nibẹ pẹlu. O tẹ̀ siwaju; laipẹ yoo tun ri apejuwe miiran niwaju; nigba ti o ba sunmọ ọ to lati ri i ka, yoo si ri i pe apejuwe naa n sọ ohun kan ti o ti kà ninu Bibeli fún un.

Jẹ ki a fi ọkàn wa wọ ọkọ̀, ki a si ma wa ọkọ naa lọ ni opopo ọ̀na ti o lọ si eti ebute. A le ri ọkọ̀ gẹdu nlanlà lọkankan ti a ti to igi gẹdú ti o tobi pupọ sinu wọn ti wọn si n lọ si ile-ẹ̀rọ. Lẹsẹkẹsẹ ẹsẹ ọrọ Iwe Mimọ́ yii yoo wá sinu ọkàn wa pe ni ọjọ imurasilẹ Rẹ̀, "igi firi li a o si mì titi" (Nahumu 2:3). A n wa ọkọ wa lọ, bẹẹni lojiji niwaju wa a ri i pe ọ̀pọlọpọ ọkọ duro loju ọnà, bi a si ti duro a ri i pe ọkọ meji ti kọlu ara wọn. Lẹẹkan si i a tun ranti pe "iwe-atọna" wa sọ fun wa pe "Ariwo kẹkẹ́ ni igboro, nwọn o si ma gbún ara wọn ni ọna gbigboro." A si gbà ni ọkàn wa pe eyi ni ọjọ imurasilẹ Rẹ̀.

A gbọ́ pe awọn ti o wa ọkọ wọnni ti mu ọti lile eyi ti i ṣe "àmi" miiran pe eyi jẹ́ akoko ti o ṣiwaju ipadabọ Jesu si ayé. Bẹẹni ọ̀rọ-odi n ti ẹnu awọn ti afẹ-ayé ti sọ di wère, ti o wà ninu ọkọ naa jade, eyi pẹlu si tun jẹ ami igbà ikẹyin (2 Timoteu 3:1-5).

**Awọn Àmi Miiran**

Ẹ jẹ ki a wò yika ki a ṣakiyesi awọn "ami" miiran ti a le ri. A kà ninu 2 Timoteu 3:1, 2, pe "ni ikẹhin ọjọ" awọn ọmọde yoo jẹ aṣaigbọran si obi. Njẹ o ti duro ki o si ronu pe nigba ti o ba ṣaigbọran iwọ n ṣe ohun naa ti Bibeli sọ pe ọ̀pọlọpọ awọn ọmọde yoo maa ṣe ṣiwaju bibọ Jesu? Laiṣe aniani, o jẹ ohun pataki julọ fun irú awọn ọmọde bẹẹ lati ri igbala kiakia, ki wọn si bẹ awọn obi wọn pe ki wọn dari aigbọran wọn ji wọn, ki wọn si murasilẹ ni kikun de bibọ Oluwa. Iwọ ha jẹ alailọpẹ́ si Ọlọrun fun aabo Rẹ̀ lori ẹmi rẹ? Iwọ ha jẹ alailọpẹ́ si awọn obi rẹ ati awọn ọrẹ rẹ fun iṣoore wọn si ọ ati fun ọ̀pọlọpọ nnkan rere ti o ni laye yii? Bi o ba ri bẹẹ, iwọ naa pẹlu awọn eniyan ti wọn n fi idi "amì" miiran mulẹ pe igbà ikẹyin ni a wà yii.

Ọpọlọpọ eniyan ni wọn ki i tẹriba nidi tabili wọn lati gbadura ati lati dupẹ lọwọ Ọlọrun fun ounjẹ ti O rán si wọn. "Eyi ni ki o mọ̀, pe ni ikẹhin ọjọ … awọn enia jẹ … alai lọpẹ" (2 Timoteu 3:2). Awọn Onigbagbọ́ miiran paapaa ki iní ọkàn ọpẹ́, wọn gbagbe pe "gbogbo ẹ̀bun rere ati gbogbo ẹ̀bun pipé lati oke li o ti wá, o si nsọkalẹ lati ọdọ Baba imọlẹ wá" (Jakọbu 1:17).

Iwọ ha jẹ ọdọmọde Onigbagbọ́ ti n lọ si ile-ẹkọ ti gbogboo-gbo? Boya iwọ n ri i ti awọn ọmọde ti ko i ti ri igbala n huwa ti kò tọ si ọ ti won si n fi ọ ṣe ẹlẹya nitori pe iwọ ki iba wọn lọ si ile-eré, ile-ijó, tabi eré bọọlù, ati awọn eré idaraya miiran gbogbo. Iwọ ki i ṣe aṣerége ninu aṣọ wiwọ bi awọn ẹlẹṣẹ ti n ṣe, bẹẹni iwọ ki ifi ohun ọṣọ́ sara tabi ki o kun ète, lé tiroo tabi kun atike. A le ta ọ nù nitori pe o yatọ ninu iṣe ati iwọṣọ rẹ. Eyi pẹlu jẹ "ami" miiran nitori Ọrọ Ọlọrun wi pe nikẹyin ọjọ awọn eniyan yoo jẹ "alainifẹ-ohun-rere." Ṣugbọn ọjọ kan n bọ̀ nigba ti Oluwa yoo rẹrin idaamu awọn eniyan buburu, awọn ti wọn kò ronupiwada ẹ̀ṣẹ wọn.

Irin ajò yii le dopin laipẹ; gẹgẹ bi arinrin-ajò ni si ti ri ọ̀pọlọpọ apejuwe lati fi hàn pe ilu naa kò jinna mọ́, bakan naa ni Onigbagbọ n ri ọ̀pọlọpọ awọn ami ti o n fi hàn an pe Ilu Ọlorun ni wà nitosi.

**Eyi ti O ṣe Pataki Julọ**

Bi iwọ kò ba ti murasilẹ fun bibọ̀ Jesu, maṣe fi ọjọ imurasilẹ dọ́la rara. Fi gbogbo àya rẹ wá Oluwa; wá ayọ̀ ni ti o n ti ọdọ Rẹ̀ nikanṣoṣo wá. Nigba naa ni iwọ wà ni oju ọ̀na ti o n lọ si Ọrun. Nigba ti a ba gbà ọ la, o nilati wá isọdimimọ́ ki o si ri i gbà ati ifi Ẹmi Mimọ́ ati iná wọ ni.

"Awọn ami" bibọ Jesu laipẹ n pọ̀ si i lojoojumọ -- nitori naa opin ọ̀na kò jinna mọ́! O le pẹ ju bi o ti ro lọ. O ha ti murasilẹ?

## AWỌN IBEERE

1 Ibeere wo ni awọn ọmọ-ẹyin beere lọwọ Jesu lori Oke Olifi?

2 Idahun wo ni Jesu fi fun wọn?

3 Darukọ alakọsilẹ kan ninu Majẹmu Lailai ti o sọ̀rọ bakan naa nipa awọn àmi igbà ikẹyin.

4 Ki ni o sọ asọtẹlẹ nipa rẹ̀?

5 Bawo ni a ṣe mọ̀ pe nnkan wọnyii ti ṣẹlẹ?

6 Ki ni ohun ti o yẹ fun wa lati ṣe ki a ba le wà ni imurasilẹ lati pade Jesu nigba ti O bá dé?

7 Ki ni ṣe ti o fi jẹ ohun pataki lati murasilẹ ati lati wa bẹẹ ninu imurasilẹ?

8 Ki ni awọn ẹlẹgan n wi?

9 Ki ni yoo ṣẹlẹ si awọn ti o ba kù silẹ?

10 Ki ni yoo jẹ́ ère awọn ti wọn murasilẹ?

## AWỌN ÀMÌ IPADABỌ OLUWA

**Nahumu 2:3, 4; 2 Timoteu 3:1-5; 2 Peteru 3:3, 4;**

## Jakọbu 5:7, 8; Matteu 24:3-28

## ẸKỌ 362 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nitori gẹgẹ bi manamana ti ikọ lati ila-õrun, ti isi mọlẹ de iwọ-õrun; bẹ̃ni wiwá Ọmọ-enia yio ri pẹlu" (Matteu 24:27).**

### Lori Oke Olifi

Lori Oke Olifi yii gan, nibiti Jesu yoo gbe goke lọ si Ọrun, ni Jesu joko lọjọ kan pẹlu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀. "Sọ fun wa," ni wọn wi fun Jesu "kini yio si ṣe àmi wiwa rẹ, ati ti opin aiye?" Nigba naa ni Jesu sọ fun wọn nipa ogun, iyàn ati isẹlẹ gbogbo ti yoo wá sori ilẹ ayé ṣiwaju bibọ Rẹ̀. O sọ nipa awọn èké wolii, tabi awọn oniwaasu èké ti yoo tan awọn eniyan jẹ, ati nipa ẹ̀ṣẹ buburu ati wahala ti yoo wá sori ayé. O wi pe "A o si wasu ihinrere ijọba yi ni gbogbo aiye lati ṣe ẹri fun gbogbo orilẹ-ède; nigbana li opin yio si de."

Lẹyin eyi lọjọ kan Jesu tun wà pẹlu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lẹẹkan si i lori Oke Olifi, nibiti awọsanma gbé gbà A lọ si Ọrun. "Jesu na yi, ti a gbà soke ọ̀run kuro lọwọ nyin, yio pada bẽ gẹgẹ bi ẹ ti ri i ti o nlọ si ọrun," ni ọ̀rọ ti awọn ọkunrin meji alaṣọ àla ti o duro leti ọdọ wọn sọ fun wọn (Iṣe Awọn Apọsteli 1:11).

### Onigbagbọ́ ati Alaigbagbọ́

Bi o tilẹ jẹ pe ẹgbaa ọdun ti rekọja lẹyin ọjọ iyanu nì, sibẹ nigba gbogbo ni awọn eniyan ti wà ti wọn n ṣọna, ti wọn n duro, ti wọn si n pongbẹ fun bibọ̀ Jesu. Lode oni, Onigbagbọ́ tootọ kò tun n wi pe, "Sọ fun wa, kini yio si ṣe ami wiwá rẹ?" ṣugbọn oun a maa wo inu Iwe Mimọ́ Ọlọrun fun awọn àmì wọnni, bi o si ti n ṣakiyesi ohun ti n ṣẹlẹ oun yoo mọ̀ daju pe gbogbo ami wọnyii ni o ti ṣẹlẹ̀. Ki ni gbogbo nnkan wọnyii n sọ fun wa? Eyi ni pe Jesu le dé nigbakuugba!

Ẹ maṣe jẹ ki a wa laaarin awọn ti wọn n ṣẹfẹ ti wọn wi pe: "Nibo ni ileri wiwa rẹ̀ gbé wà? lati igbati awọn baba ti sùn, ohun gbogbo nlọ bi nwọn ti wà ri lati igba ọjọ iwa" (2 Peteru 3:4). Ileri naa wà ninu Ọrọ Ọlọrun, a si gbagbọ́ pe a o wà laaye a o si ri Jesu nigba ti o ba n pada bọ̀.

Nitori pe ohun kan ko i ti ṣẹlẹ kò fi hàn pe ohun naa ki yoo ṣẹlẹ. Ṣaaju Ikun-omi, nigba ti Noa kan ọkọ nì, awọn eniyan kò gbagbọ́ pe ikun-omi yoo dé. Wọn n fi Noa ṣẹlẹya gẹgẹ bi wọn ti n fi awọn oniwaasu ododo ṣẹsin lode oni. Ṣugbọn lojiji, "omi de, ti o gbá gbogbo wọn lọ" (Matteu 24:39).

"Gẹgẹ bẹ̃ni wiwa Ọmọ-enia yio ri pẹlu" (Matteu 24:39). Lojiji! Fun awọn ti kò fi oju sọna fun bibọ̀ Rẹ̀. Gẹgẹ "bi ikẹkun" fun awọn ti kò wà ni imurasilẹ! (Luku 21:35). "Bi olè" fun ẹni ti kò di ara rẹ̀ ni amure (1 Tẹssalonika 5:2). "Gẹgẹ bi manamana," ti n dá eniyan niji! (Matteu 24:27). "Lãrin ọganjọ," nigba ti ohun gbogbo ṣokunkun! (Matteu 25:6).

Ọpọlọpọ "àmi" ni o wà ti o n kọ́ wa pé bibọ̀ Jesu wà lẹyin ilẹkun. Awọn eniyan Ọlọrun ti n gbé lori ilẹ ayé ṣaaju igba Kristi sọ̀rọ nipa awọn ohun ti yoo ṣẹlẹ ni ikẹyin ọjọ. Awọn ami ti Jesu sọtẹlẹ fun awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀ -- ogun, isẹ̀lẹ, idaamu – gbogbo wọn ni o ti ṣẹlẹ̀. Ọpọlọpọ awọn ọdọmọde lode oni ni o le ranti igbati wọn dagbere fun ẹgbọn wọn ọkunrin tabi baba wọn ti o lọ si ogun. Gbogbo wa ni o ti gbọ́ nipa isẹlẹ̀ ti o si ti ṣiṣẹ iparun lọpọlọpọ ni akoko tiwa yii, ati nipa iyà ati wahala ti ọ̀pọlọpọ eniyan wà ninu rẹ̀ lori ilẹ ayé.

### Awọn Arinrin Ajò

Njẹ o ṣakiyesi nigba ti o n rin irin-ajo lọ si ilu kan pe bi o ti n sunmọ ilu naa ni o n ri ọ̀pọlọpọ apejuwe ti o n fi hàn pe iwọ fẹrẹ dé bẹ? Awọn apejuwe miiran n sọ nipa ile-èro tabi ile-ounjẹ ti o wà ni ilu naa; awọn apejuwe miiran n fi bi ilu naa ti jinna tó hàn; bẹẹni awọn apejuwe miiran a maa sọ fun wa akoko ti a le lò ki a tó dé ilu naa.

Lonii a n rin irin-ajò. Olukuluku wa ni o n rin irin ajò lọ si Ayeraye, awọn ohun itọka ti o hàn gbangba si wa ni oju ọna Iye naa. Laiṣe aniani, Onigbagbọ́ arinrin-ajò naa ni iwe-amunimọna, iwe-aworan-apẹẹrẹ ilẹ ati ẹrọ amunimọna, bẹẹni a si maa farabalẹ̀ ṣafiyesi iwe-amunimọna rẹ̀, ani Bibeli. Gẹgẹ bi o si ti n rin ọ̀na ayé lọ a maa ri awọn ami oju-ọna. Yoo wo inu iwe-amunimọna rẹ̀. Yoo si ri i dajudaju pe ibiti oun dé yii wà ninu iwe-amunimana naa, bẹẹni lẹba ọna ami ọ̀na naa si wà nibẹ pẹlu. O tẹ̀ siwaju; laipẹ yoo tun ri apejuwe miiran niwaju; nigba ti o ba sunmọ ọ to lati ri i ka, yoo si ri i pe apejuwe naa n sọ ohun kan ti o ti kà ninu Bibeli fún un.

Jẹ ki a fi ọkàn wa wọ ọkọ̀, ki a si ma wa ọkọ naa lọ ni opopo ọ̀na ti o lọ si eti ebute. A le ri ọkọ̀ gẹdu nlanlà lọkankan ti a ti to igi gẹdú ti o tobi pupọ sinu wọn ti wọn si n lọ si ile-ẹ̀rọ. Lẹsẹkẹsẹ ẹsẹ ọrọ Iwe Mimọ́ yii yoo wá sinu ọkàn wa pe ni ọjọ imurasilẹ Rẹ̀, "igi firi li a o si mì titi" (Nahumu 2:3). A n wa

ọkọ wa lọ, bẹẹni lojiji niwaju wa a ri i pe ọ̀pọlọpọ ọkọ duro loju ọnà, bi a si ti duro a ri i pe ọkọ meji ti kọlu ara wọn. Lẹẹkan si i a tun ranti pe "iwe-atọna" wa sọ fun wa pe "Ariwo kẹkẹ́ ni igboro, nwọn o si ma gbún ara wọn ni ọna gbigboro." A si gbà ni ọkàn wa pe eyi ni ọjọ imurasilẹ Rẹ̀.

A gbọ́ pe awọn ti o wa ọkọ wọnni ti mu ọti lile eyi ti i ṣe "àmi" miiran pe eyi jẹ́ akoko ti o ṣiwaju ipadabọ Jesu si ayé. Bẹẹni ọ̀rọ-odi n ti ẹnu awọn ti afẹ-ayé ti sọ di wère, ti o wà ninu ọkọ naa jade, eyi pẹlu si tun jẹ ami igbà ikẹyin (2 Timoteu 3:1-5).

**Awọn Àmi Miiran**

Ẹ jẹ ki a wò yika ki a ṣakiyesi awọn "ami" miiran ti a le ri. A kà ninu 2 Timoteu 3:1, 2, pe "ni ikẹhin ọjọ" awọn ọmọde yoo jẹ aṣaigbọran si obi. Njẹ o ti duro ki o si ronu pe nigba ti o ba ṣaigbọran iwọ n ṣe ohun naa ti Bibeli sọ pe ọ̀pọlọpọ awọn ọmọde yoo maa ṣe ṣiwaju bibọ Jesu? Laiṣe aniani, o jẹ ohun pataki julọ fun irú awọn ọmọde bẹẹ lati ri igbala kiakia, ki wọn si bẹ awọn obi wọn pe ki wọn dari aigbọran wọn ji wọn, ki wọn si murasilẹ ni kikun de bibọ Oluwa. Iwọ ha jẹ alailọpẹ́ si Ọlọrun fun aabo Rẹ̀ lori ẹmi rẹ? Iwọ ha jẹ alailọpẹ́ si awọn obi rẹ ati awọn ọrẹ rẹ fun iṣoore wọn si ọ ati fun ọ̀pọlọpọ nnkan rere ti o ni laye yii? Bi o ba ri bẹẹ, iwọ naa pẹlu awọn eniyan ti wọn n fi idi "amì" miiran mulẹ pe igbà ikẹyin ni a wà yii.

Ọpọlọpọ eniyan ni wọn ki i tẹriba nidi tabili wọn lati gbadura ati lati dupẹ lọwọ Ọlọrun fun ounjẹ ti O rán si wọn. "Eyi ni ki o mọ̀, pe ni ikẹhin ọjọ … awọn enia jẹ … alai lọpẹ" (2 Timoteu 3:2). Awọn Onigbagbọ́ miiran paapaa ki iní ọkàn ọpẹ́, wọn gbagbe pe "gbogbo ẹ̀bun rere ati gbogbo ẹ̀bun pipé lati oke li o ti wá, o si nsọkalẹ lati ọdọ Baba imọlẹ wá" (Jakọbu 1:17).

Iwọ ha jẹ ọdọmọde Onigbagbọ́ ti n lọ si ile-ẹkọ ti gbogboo-gbo? Boya iwọ n ri i ti awọn ọmọde ti ko i ti ri igbala n huwa ti kò tọ si ọ ti won si n fi ọ ṣe ẹlẹya nitori pe iwọ ki iba wọn lọ si ile-eré, ile-ijó, tabi eré bọọlù, ati awọn eré idaraya miiran gbogbo. Iwọ ki i ṣe aṣerége ninu aṣọ wiwọ bi awọn ẹlẹṣẹ ti n ṣe, bẹẹni iwọ ki ifi ohun ọṣọ́ sara tabi ki o kun ète, lé tiroo tabi kun atike. A le ta ọ nù nitori pe o yatọ ninu iṣe ati iwọṣọ rẹ. Eyi pẹlu jẹ "ami" miiran nitori Ọrọ Ọlọrun wi pe nikẹyin ọjọ awọn eniyan yoo jẹ "alainifẹ-ohun-rere." Ṣugbọn ọjọ kan n bọ̀ nigba ti Oluwa yoo rẹrin idaamu awọn eniyan buburu, awọn ti wọn kò ronupiwada ẹ̀ṣẹ wọn.

Irin ajò yii le dopin laipẹ; gẹgẹ bi arinrin-ajò ni si ti ri ọ̀pọlọpọ apejuwe lati fi hàn pe ilu naa kò jinna mọ́, bakan naa ni Onigbagbọ n ri ọ̀pọlọpọ awọn ami ti o n fi hàn an pe Ilu Ọlorun ni wà nitosi.

**Eyi ti O ṣe Pataki Julọ**

Bi iwọ kò ba ti murasilẹ fun bibọ̀ Jesu, maṣe fi ọjọ imurasilẹ dọ́la rara. Fi gbogbo àya rẹ wá Oluwa; wá ayọ̀ ni ti o n ti ọdọ Rẹ̀ nikanṣoṣo wá. Nigba naa ni iwọ wà ni oju ọ̀na ti o n lọ si Ọrun. Nigba ti a ba gbà ọ la, o nilati wá isọdimimọ́ ki o si ri i gbà ati ifi Ẹmi Mimọ́ ati iná wọ ni.

"Awọn ami" bibọ Jesu laipẹ n pọ̀ si i lojoojumọ -- nitori naa opin ọ̀na kò jinna mọ́! O le pẹ ju bi o ti ro lọ. O ha ti murasilẹ?

**AWỌN IBEERE**

1. Ibeere wo ni awọn ọmọ-ẹyin beere lọwọ Jesu lori Oke Olifi?
2. Idahun wo ni Jesu fi fun wọn?
3. Darukọ alakọsilẹ kan ninu Majẹmu Lailai ti o sọ̀rọ bakan naa nipa awọn àmi igbà ikẹyin.
4. Ki ni o sọ asọtẹlẹ nipa rẹ̀?
5. Bawo ni a ṣe mọ̀ pe nnkan wọnyii ti ṣẹlẹ?
6. Ki ni ohun ti o yẹ fun wa lati ṣe ki a ba le wà ni imurasilẹ lati pade Jesu nigba ti O bá dé?
7. Ki ni ṣe ti o fi jẹ ohun pataki lati murasilẹ ati lati wa bẹẹ ninu imurasilẹ?
8. Ki ni awọn ẹlẹgan n wi?
9. Ki ni yoo ṣẹlẹ si awọn ti o ba kù silẹ?
10. Ki ni yoo jẹ́ ère awọn ti wọn murasilẹ?

## AWỌN ÀMÌ IPADABỌ OLUWA

**Nahumu 2:3, 4; 2 Timoteu 3:1-5; 2 Peteru 3:3, 4;**

**Jakọbu 5:7, 8; Matteu 24:3-28**

**ẸKỌ 362 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: “Nitori gẹgẹ bi manamana ti ikọ lati ila-õrun, ti isi mọlẹ de iwọ-õrun; bẽni wiwá Ọmọ-enia yio ri pẹlu” (Matteu 24:27).**

**Lori Oke Olifi**

Lori Oke Olifi yii gan, nibiti Jesu yoo gbe goke lọ si Ọrun, ni Jesu joko lọjọ kan pẹlu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀. “Sọ fun wa,” ni wọn wi fun Jesu “kini yio si ṣe àmi wiwa rẹ, ati ti opin aiye?” Nigba naa ni Jesu sọ fun wọn nipa ogun, iyàn ati isẹlẹ gbogbo ti yoo wá sori ilẹ ayé ṣiwaju bibọ Rẹ̀. O sọ nipa awọn èké wolii, tabi awọn oniwaasu èké ti yoo tan awọn eniyan jẹ, ati nipa ẹ̀ṣẹ buburu ati wahala ti yoo wá sori ayé. O wi pe “A o si wasu ihinrere ijọba yi ni gbogbo aiye lati ṣe ẹri fun gbogbo orilẹ-ède; nigbana li opin yio si de.”

Lẹyin eyi lọjọ kan Jesu tun wà pẹlu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lẹẹkan si i lori Oke Olifi, nibiti awọsanma gbé gbà A lọ si Ọrun. “Jesu na yi, ti a gbà soke ọ̀run kuro lọwọ nyin, yio pada bẽ gẹgẹ bi ẹ ti ri i ti o nlọ si ọrun,” ni ọ̀rọ ti awọn ọkunrin meji alaṣọ àla ti o duro leti ọdọ wọn sọ fun wọn (Iṣe Awọn Apọsteli 1:11).

**Onigbagbọ́ ati Alaigbagbọ́**

Bi o tilẹ jẹ pe ẹgbaa ọdun ti rekọja lẹyin ọjọ iyanu nì, sibẹ nigba gbogbo ni awọn eniyan ti wà ti wọn n ṣọna, ti wọn n duro, ti wọn si n pongbẹ fun bibọ̀ Jesu. Lode oni, Onigbagbọ́ tootọ kò tun n wi pe, “Sọ fun wa, kini yio si ṣe ami wiwá rẹ?” ṣugbọn oun a maa wo inu Iwe Mimọ́ Ọlọrun fun awọn àmì wọnni, bi o si ti n ṣakiyesi ohun ti n ṣẹlẹ oun yoo mọ̀ daju pe gbogbo ami wọnyii ni o ti ṣẹlẹ̀. Ki ni gbogbo nnkan wọnyii n sọ fun wa? Eyi ni pe Jesu le dé nigbakuugba!

Ẹ maṣe jẹ ki a wa laaarin awọn ti wọn n ṣẹfẹ ti wọn wi pe: “Nibo ni ileri wiwa rẹ̀ gbé wà? lati igbati awọn baba ti sùn, ohun gbogbo nlọ bi nwọn ti wà ri lati igba ọjọ iwa” (2 Peteru 3:4). Ileri naa wà ninu Ọrọ Ọlọrun, a si gbagbọ́ pe a o wà laaye a o si ri Jesu nigba ti o ba n pada bọ̀.

Nitori pe ohun kan ko i ti ṣẹlẹ kò fi hàn pe ohun naa ki yoo ṣẹlẹ. Ṣaaju Ikun-omi, nigba ti Noa kan ọkọ nì, awọn eniyan kò gbagbọ́ pe ikun-omi yoo dé. Wọn n fi Noa ṣẹlẹya gẹgẹ bi wọn ti n fi awọn oniwaasu ododo ṣẹsin lode oni. Ṣugbọn lojiji, “omi de, ti o gbá gbogbo wọn lọ” (Matteu 24:39).

“Gẹgẹ bẽni wiwa Ọmọ-enia yio ri pẹlu” (Matteu 24:39). Lojiji! Fun awọn ti kò fi oju sọna fun bibọ̀ Rẹ̀. Gẹgẹ “bi ikẹkun” fun awọn ti kò wà ni imurasilẹ! (Luku 21:35). “Bi olè” fun ẹni ti kò di ara rẹ̀ ni amure (1 Tẹssalonika 5:2). “Gẹgẹ bi manamana,” ti n dá eniyan niji! (Matteu 24:27). “Lãrin ọganjọ,” nigba ti ohun gbogbo ṣokunkun! (Matteu 25:6).

Ọpọlọpọ “àmi” ni o wà ti o n kọ́ wa pé bibọ̀ Jesu wà lẹyin ilẹkun. Awọn eniyan Ọlọrun ti n gbé lori ilẹ ayé ṣaaju igba Kristi sọ̀rọ nipa awọn ohun ti yoo ṣẹlẹ ni ikẹyin ọjọ. Awọn ami ti Jesu sọtẹlẹ fun awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀ -- ogun, isẹ̀lẹ, idaamu – gbogbo wọn ni o ti ṣẹlẹ̀. Ọpọlọpọ awọn ọdọmọde lode oni ni o le ranti igbati wọn dagbere fun ẹgbọn wọn ọkunrin tabi baba wọn ti o lọ si ogun. Gbogbo wa ni o ti gbọ́ nipa isẹlẹ̀ ti o si ti ṣiṣẹ iparun lọpọlọpọ ni akoko tiwa yii, ati nipa iyà ati wahala ti ọ̀pọlọpọ eniyan wà ninu rẹ̀ lori ilẹ ayé.

**Awọn Arinrin Ajò**

Njẹ o ṣakiyesi nigba ti o n rin irin-ajo lọ si ilu kan pe bi o ti n sunmọ ilu naa ni o n ri ọ̀pọlọpọ apejuwe ti o n fi hàn pe iwọ fẹrẹ dé bẹ? Awọn apejuwe miiran n sọ nipa ile-èro tabi ile-ounjẹ ti o wà ni ilu naa; awọn apejuwe miiran n fi bi ilu naa ti jinna tó hàn; bẹẽni awọn apejuwe miiran a maa sọ fun wa akoko ti a le lò ki a tó dé ilu naa.

Lonii a n rin irin-ajò. Olukuluku wa ni o n rin irin ajò lọ si Ayeraye, awọn ohun itọka ti o hàn gbangba si wa ni oju ọna Iye naa. Laiṣe aniani, Onigbagbọ́ arinrin-ajò naa ni iwe-amunimọna, iwe-aworan-apẹẹrẹ ilẹ ati ẹrọ amunimọna, bẹẽni a si maa farabalẹ̀ ṣafiyesi iwe-amunimọna rẹ̀, ani Bibeli. Gẹgẹ bi o si ti n rin ọ̀na ayé lọ a maa ri awọn ami oju-ọna. Yoo wo inu iwe-amunimọna rẹ̀. Yoo si ri i dajudaju pe ibiti oun dé yii wà ninu iwe-amunimana naa, bẹẽni lẹba ọna ami ọ̀na naa si wà nibẹ pẹlu. O tẹ̀ siwaju; laipẹ yoo tun ri apejuwe miiran niwaju; nigba ti o ba sunmọ ọ to lati ri i ka, yoo si ri i pe apejuwe naa n sọ ohun kan ti o ti kà ninu Bibeli fún un.

Jẹ ki a fi ọkàn wa wọ ọkọ̀, ki a si ma wa ọkọ naa lọ ni opopo ọ̀na ti o lọ si eti ebute. A le ri ọkọ̀ gẹdu nlanlà lọkankan ti a ti to igi gẹdú ti o tobi pupọ sinu wọn ti wọn si n lọ si ile-ẹ̀rọ. Lẹsẹkẹsẹ ẹsẹ ọrọ Iwe Mimọ́ yii yoo wá sinu ọkàn wa pe ni ọjọ imurasilẹ Rẹ̀, “igi firi li a o si mì titi” (Nahumu 2:3). A n wa ọkọ wa lọ, bẹẽni lojiji niwaju wa a ri i pe ọ̀pọlọpọ ọkọ duro loju ọnà, bi a si ti duro a ri i pe ọkọ meji ti kọlu ara wọn. Lẹẹkan si i a tun ranti pe “iwe-atọna” wa sọ fun wa pe “Ariwo kẹké ni igboro, nwọn o si ma gbún ara wọn ni ọna gbigboro.” A si gbà ni ọkàn wa pe eyi ni ọjọ imurasilẹ Rẹ̀.

A gbọ́ pe awọn ti o wa ọkọ wọnni ti mu ọti lile eyi ti i ṣe "àmi" miiran pe eyi jẹ́ akoko ti o ṣiwaju ipadabọ Jesu si ayé. Bẹẹni ọ̀rọ-odi n ti ẹnu awọn ti afẹ-ayé ti sọ di wère, ti o wà ninu ọkọ naa jade, eyi pẹlu si tun jẹ ami igbà ikẹyin (2 Timoteu 3:1-5).

**Awọn Àmi Miiran**

Ẹ jẹ ki a wò yika ki a ṣakiyesi awọn "ami" miiran ti a le ri. A kà ninu 2 Timoteu 3:1, 2, pe "ni ikẹhin ọjọ" awọn ọmọde yoo jẹ aṣaigbọran si obi. Njẹ o ti duro ki o si ronu pe nigba ti o ba ṣaigbọran iwọ n ṣe ohun naa ti Bibeli sọ pe ọ̀pọlọpọ awọn ọmọde yoo maa ṣe ṣiwaju bibọ Jesu? Laiṣe aniani, o jẹ ohun pataki julọ fun irú awọn ọmọde bẹẹ lati ri igbala kiakia, ki wọn si bẹ awọn obi wọn pe ki wọn dari aigbọran wọn ji wọn, ki wọn si murasilẹ ni kikun de bibọ Oluwa. Iwọ ha jẹ alailọpẹ́ si Ọlọrun fun aabo Rẹ̀ lori ẹmi rẹ? Iwọ ha jẹ alailọpẹ́ si awọn obi rẹ ati awọn ọrẹ rẹ fun iṣoore wọn si ọ ati fun ọ̀pọlọpọ nnkan rere ti o ni laye yii? Bi o ba ri bẹẹ, iwọ naa pẹlu awọn eniyan ti wọn n fi idi "amì" miiran mulẹ pe igbà ikẹyin ni a wà yii.

Ọpọlọpọ eniyan ni wọn ki i tẹriba nidi tabili wọn lati gbadura ati lati dupẹ lọwọ Ọlọrun fun ounjẹ ti O rán si wọn. "Eyi ni ki o mọ̀, pe ni ikẹhin ọjọ … awọn enia jẹ … alai lọpẹ" (2 Timoteu 3:2). Awọn Onigbagbọ́ miiran paapaa ki iní ọkàn ọpẹ́, wọn gbagbe pe "gbogbo ẹ̀bun rere ati gbogbo ẹ̀bun pipé lati oke li o ti wá, o si nsọkalẹ lati ọdọ Baba imọlẹ wá" (Jakọbu 1:17).

Iwọ ha jẹ ọdọmọde Onigbagbọ́ ti n lọ si ile-ẹkọ ti gbogboo-gbo? Boya iwọ n ri i ti awọn ọmọde ti ko i ti ri igbala n huwa ti kò tọ si ọ ti won si n fi ọ ṣe ẹlẹya nitori pe iwọ ki iba wọn lọ si ile-eré, ile-ijó, tabi eré bọọlù, ati awọn eré idaraya miiran gbogbo. Iwọ ki i ṣe aṣerége ninu aṣọ wiwọ bi awọn ẹlẹṣẹ ti n ṣe, bẹẹni iwọ ki ifi ohun ọṣọ́ sara tabi ki o kun ète, lé tiroo tabi kun atike. A le ta ọ nù nitori pe o yatọ ninu iṣe ati iwọṣọ rẹ. Eyi pẹlu jẹ "ami" miiran nitori Ọrọ Ọlọrun wi pe nikẹyin ọjọ awọn eniyan yoo jẹ "alainifẹ-ohun-rere." Ṣugbọn ọjọ kan n bọ̀ nigba ti Oluwa yoo rẹrin idaamu awọn eniyan buburu, awọn ti wọn kò ronupiwada ẹ̀ṣẹ wọn.

Irin ajò yii le dopin laipẹ; gẹgẹ bi arinrin-ajò ni si ti ri ọ̀pọlọpọ apejuwe lati fi hàn pe ilu naa kò jinna mọ́, bakan naa ni Onigbagbọ n ri ọ̀pọlọpọ awọn ami ti o n fi hàn an pe Ilu Ọlorun ni wà nitosi.

**Eyi ti O ṣe Pataki Julọ**

Bi iwọ kò ba ti murasilẹ fun bibọ̀ Jesu, maṣe fi ọjọ imurasilẹ dọ́la rara. Fi gbogbo àya rẹ wá Oluwa; wá ayọ̀ ni ti o n ti ọdọ Rẹ̀ nikanṣoṣo wá. Nigba naa ni iwọ wà ni oju ọ̀na ti o n lọ si Ọrun. Nigba ti a ba gbà ọ la, o nilati wá isọdimimọ́ ki o si ri i gbà ati ifi Ẹmi Mimọ́ ati iná wọ ni.

"Awọn ami" bibọ Jesu laipẹ n pọ̀ si i lojoojumọ -- nitori naa opin ọ̀na kò jinna mọ́! O le pẹ ju bi o ti ro lọ. O ha ti murasilẹ?

**AWỌN IBEERE**

1 Ibeere wo ni awọn ọmọ-ẹyin beere lọwọ Jesu lori Oke Olifi?

2 Idahun wo ni Jesu fi fun wọn?

3 Darukọ alakọsilẹ kan ninu Majẹmu Lailai ti o sọ̀rọ bakan naa nipa awọn àmi igbà ikẹyin.

4 Ki ni o sọ asọtẹlẹ nipa rẹ̀?

5 Bawo ni a ṣe mọ̀ pe nnkan wọnyii ti ṣẹlẹ?

6 Ki ni ohun ti o yẹ fun wa lati ṣe ki a ba le wà ni imurasilẹ lati pade Jesu nigba ti O bá dé?

7 Ki ni ṣe ti o fi jẹ ohun pataki lati murasilẹ ati lati wa bẹẹ ninu imurasilẹ?

8 Ki ni awọn ẹlẹgan n wi?

9 Ki ni yoo ṣẹlẹ si awọn ti o ba kù silẹ?

10 Ki ni yoo jẹ́ ère awọn ti wọn murasilẹ?